The ... Secretary to the Government


Eri Ọgbẹni Herbert Macaulay mi ẹ nihin.

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. NO. 286 SATURDAY AUGUST 4 1928 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



NIGERIAN SECRETARIAT 21 AUG. 1928


## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

**N.B.**—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

## EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nję ki o ri aye wu arun mi silę.


LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
Dr. Earl S. Sloan
SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
mists and Patent Medicine Dealers
Carton adopted 1916.
s for Great Britain
FASSETT & JOHNSON,
Road, London, E.C.
RED ONLY BY
CORPORATED)
ST. LOUIS. TORONTO. CAN.
ome Office. BOSTON
in United States of America
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Keep away from
Fire or Flame
TO
STOP YOUR
ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale Fassett & Johnson L^td.
Clerkenwell R^d. London.
England

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA.
*Office* 24, Williams Street
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | [illegible] |

Ẹ li owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### ALABỌFẸ OBINRIN ETIGBO.

Ni dede agogo mejila oru ọjọ Jimọ ọsẹ tokọja ni obinrin kan ti o ro dẹdẹ ti o gba dẹdẹ nkigbe Ọlọpa o! Ọlọpa o!! ni butubutu ti o wa ni eti ẹrọ omi-Iju ni odo Oluṣi ti o si ji gbogbo aladugbo kalẹ nigbati Ọpa-Ọba kan si de ti o bere lọwọ ojigọbi yi pe kilode, eju gba gbogbo enia ti o wa nibẹ ti nigbati obinrin yi bẹrẹ si ọrọ siso pẹlu oju rire pepe, pe on gba iwa-aitọ fun awọn ọkọnrin mẹta ninu ile kanna lẹkanna ati pe alaifẹ ṣika alukawani ti ọkan ninu wọn ba on ṣe, lo mu on kibosi bẹ; Ọlọpa bere ọrọ lọwọ ọkọnrin ti obinrin na nsọrọ rẹ bayi, ṣugbọn onitọhun tako ọrọ obirin na o si ni on ko kọ bi Ọlọpa ba ko ton tobinrin na lọ si Ita Tinubu ngbọ kini oku ti nwa bikoṣe agọ warawere bẹni Ọpa-Ọba na mu wọn lọ, rẹrẹ o di Ibudo wọn ni Ita Iyalode.

Dajudaju amunibuni pọ ninu awọn obinrin miran l'Eko.

## DUNIYAN—LABARI.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

### Ẹ KI ABỌ SA.

A gbọ wipe Onidajọ Agba Sir Ralph Combe C.J., ti pada de larin ọsẹ to kọja lati ọna ilu oke ti o tilọ fun ẹjọ Ganran—Alafia kọ ni ẹ de?

### ADAJỌ PETRIDES.

Bẹni a si tun gbọ wipe Onidajọ Patrides ba ọkọ "Abinsi" lọ si ilu Calabar lọjọ Alamisi ijẹwa ti nṣe ọjọ kẹrindin-logbon oṣu July to kọja yi—ọna 're o!

### IKU IBIKUNLE AKITOYE.

Gbukẹ li ekiki iku Ibikunle Akitoye kan kuku ni oru ọjọ Alamisi ijẹwa moju ọjọ Jimọ ọjọ keji rẹ: nigbati o si di ni ọjọ Jimọ na li a ri iwe-ikede oku ti Ibikunle Akitoye na eyiti Oloye Obanikoro (Adamọ Akeju) mbẹ ni isalẹ rẹ gẹgẹbi Atufọ wipe nwọn o sin oku Ibikunle Akitoye na ni ọsan ọjọ Jimọ yi ni iwọn agogo mẹrin.

Ibikunle Akitoye bọ sinu Iga Idunganran gẹgẹbi Olori Ile Ado ni ọjọ kẹjo oṣu August 1925, ni waraṣẹṣa ti Ijọba ti wa Eṣugbayi Eleko kuro ni ilu—o jẹ ọdun meji oṣu mọkanla ati ọjọ mọkandinlogun ki a pe ọdun mẹta gbako ti o bọ si inu Iga Idunganran.

Iku Ibikunle Akitoye na jẹ iyanu loju ogunlọgọ enia, nitori a ko fi igba kan gbọ iroyin bi ẹnipe o nṣe amodi ki ọlọjọ to de ba a lọsẹ to kọja na. Awa enia li a nsọ wipe a ja mo nkan, ṣugbọn a ko jamọ ohunkohun loju Sati, Ẹniti o mọ igba ti Asarayilu yio wa ba olukuluku wa ti yio si mu wa lọ lati lọ si ibi ikẹhin wa.

Nitorina gbogbo aseko wa o yẹ ki a fi ma ṣe iṣẹ rere de Asarayilu—nitori ọjọ ti a ba ṣe win ninu lasegbo aiye yi ni iṣẹ ti olukuluku wa ṣe ninu gbogbo aseko wa yio tẹle wa gba-gba-gba eyiti a o si ma ka lọjọ Igbende ki Ọlọrun dẹlẹ fun Ibikunle o!

### ỌGAGUN GRAY.

A gbọ wipe oyinbo Major W. Birrell Gray (The Administrator of the Colony) lọ si Iga Idunganran pẹlu awọn Oyinbo melo miran eyiti a gbọ wipe Ọgagun Gray na lo fun ikedun ti iku Ibikunle Akitoye, o si sọrọ diẹ nipa iku oji rẹ.

### IRUFẸ ỌMỌ KILI EYI?

Iran dun wo ni owurọ ọjọ Satide to koja ni Apọngbọn Street, nigbati a gbọ wipe Iya kan pẹlu ọmọ rẹ obinrin ti nwọn wọ iporogan ni ti oniperewu bi igba ti Pẹpẹiyẹ ati ogbungbu i ba wọ'ya ija, nwọn ja titi fun iwọn idaji wakati ki ija to mu po—ṣugbon a ko fi igba kan gbọ ohun ti o fa sababi akitiyan na.

### IDAJỌ ẸJỌ ONIWE-IROHIN "DAILY NEWS" NIWAJU ADAJỌ H. A YOUNG, K.C.

Ni owurọ ọjọ Monday ọjọ 30 oṣu yi ni iwọn agogo mesan abọ, ni Onidajọ H. A. Young K.C.

da Oniwe-irohin "Lagos Daily News" lẹhi pe ki o san Adọta Pọnwun (£50) tabi ẹwọn oṣu mẹta fun ẹsun ti nwọn fi sun wipe o tẹ "Ọran otẹ ẹtu-ibọn" "The Nigerian Gun-Powder Plot" sinu iwe-irohin rẹ ti ọjọ kọkandin-logun oṣu June to kọja yi. ẹjo eyiti nwọn si bẹrẹsi ro lati ọjọ Jimọ ọjọ kọkandin-logun oṣu yi.

## ỌMỌ-ẸGBẸ DẸMỌ.

Kakiri li a ngbọ nipa ti ai pe ti ẹgbẹ "Dẹmọ" lati bi ọjọ mẹta yi tabi lati January ti ẹgbẹ ti pe gbẹhin—ati pẹlu awọn Olotu ẹgbẹ yi si nsọ ninu ajọ ti nwọn ṣe gbẹhin na wipe awọn ki yio ma pẹ tobẹ, ki nwọn to ma ṣe ipade gbogbo-gbo na.

Idahun wa fun eyi ni wipe ki ẹgbẹ ma pe laseko o dara nitoto, boya awọn ẹlomiran le ma sọ wipe owo Pọnun mẹjọ ati ṣile mẹjọ ti ẹgbẹ nsan fun "Hall" lo nmu ai pe ẹgbẹ wa laseko, agbẹdọ arara!

Ẹniti o ba ni lakayi yio ri wipe ẹgbẹ nlọ si dede, ati pẹlu o le jẹ idiwo fun awọn Olotu ẹgbẹ na nis siyi gẹgẹbi a ti le sọ, ṣugbọn a fẹ ki ẹ mọ wipe lai pẹ yi a tanmọ pe ẹgbẹ ni lati pe. A ro wipe awọn Olotu ẹgbẹ ki yio ṣe ai la sababi ohun ti ẹgbẹ to bayi ki nwọn to ṣe ipade.

## ẸGBẸ-ILU.

Nigbati Ọlọla W. A. G. Ormsby-Goore, M.P. (The under Secretary of State for the Colonies) ti ilu oyinbo fi wa si ilẹ yi ninu oṣu February 1296, ti o si pada de ilu Oyinbo o fi nhan l hun wipe awọn ẹgbẹ "Democratic Party" ko si ni ipo ẹgbẹ ti o nta karangban tabi bi tẹmbẹlẹkun kan si Ijọba loju ti on, bi a ba tilẹ nranti eyi ma ọmọ ẹgbẹ ni lati ma dun, gẹgẹbi o ti jẹ wipe awọn ẹlomiran nka ẹgbẹ Dẹmọ si ẹgbẹ ti o nta kanrangban si Ijọba.

Ni koi pẹ jọjọ yi iwe-irohin kan ngba awọn aṣaju wọn ni imọran wipe ki awọn da ẹgbẹ pataki kan silẹ lati fi ta kanrangban si ẹgbẹ "Bombata" nwọn gbagbe wipe ẹni Ọlọrun da ko ṣe fi arawe ati pẹlu di ọjọ oworo yi nwọn koi ti to da ẹgbẹ na silẹ boya nwọn si nwewe rẹ lọwọ ni.

## IMỌRAN SI ỌMỌ-ẸGBẸ DẸMỌ.

Imọran ti a fẹ fifun awọn ọmọ-ẹgbẹ na ni wipe kosi igi nla kan ti o wa ti ko ni gbongbo (Root) ati awọn ẹka (Branches) rẹ; nisisiyi ibiti ẹgbẹ "Dẹmọ" gbe ta de, Sati nkan lo mọ. Ṣugbọn gbongbo rẹ mbẹ ni ilẹ yi, a timọ dajudaju pe ṣaṣa adugbo ni ni gbogbo ilẹ yi ti kosi ọmọ-ẹgbẹ Dẹmọ na nibẹ.

Ti a ba ni ki a ma da awọn enia inu adugbo kọkan si mẹrin, idameta yio ma jẹ ọmọ-ẹgbẹ Dẹmọ, ẹtọ ni ki awọn idameta ni agbara ni ọna ẹtọ; ki a ka awọn idameta na si Ẹka ẹgbẹ: kini ohun ti o si tọ fun ẹka kọkan ni wipe ti idiwọ ba nbẹ fun gbongbo ẹgbẹ ki awọn ẹka wọnyi ni ibi ipade, nwọn le mu ẹniti nwọn ba nfẹ lati ma fi ṣe Olotu ẹka wọnyi lati inu gbongbo fun ipade ti ẹka ba nṣe.

## BANK HOLIDAY.

Ni Ọtunla Monday ọjọ kẹfa oṣu yi ni ọjọ (Bank Holiday) eyiti yio jẹ isinmi kan fun awọn ẹni oṣiṣẹ gbogbo gẹgẹbi atẹhinwa.

## ỌMỌBA ELEKO.

Ni ọjọ Alaruba ẹwẹ ti o ku ọjọ marun loni ti nṣe ọjọ kẹjo oṣu yi ni yio di ọdun mẹta gbako ti nwọn wa Ọmọba Eṣugbayi Eleko lọ si Ọyọ: ti Ibikunle Akitoye (ologbe) si di Arole Ile Ado, ibiti a mọ ni Iga Idunganran.

---

## ẸJỌ ETU IBỌN NI KOTU ỌLỌPA

### ẸRI ỌGBẸNI HERBERT MACAULEY, C.E.

Oloye ile kikọ ni mi ati wọrọkọ-wọnle ti o ni iwe aṣẹ Ọba, mo jẹ ọkan ninu ẹni meji ti a ni *Lagos Daily News*, emi lo nkọ iwe na iii ijanu mo si jẹ alabojuto rẹ, lati oṣu January to kọja, ni ọjọ karun oṣu June ni mo di alabojuto rẹ gan.

Mo mọ Eṣugbayi bi ẹni mọ owo, mo si mọ Olushọla dada, ni ọjọ 19 oṣu June ni mo ri waya kan gba lati ọdọ Ọgbẹni Hunt, mo fi iwe si la nipa jija re appeal Eṣugbayi ni Ile Ọba. Mo ranṣẹ si Eṣugbayi ni dede agogo mẹta ni ogun jọ oṣu June (20th) pe awọn adajọ da lire appeal rẹ, pe ki o si gba owo irin ẹsẹ, ṣugbọn mo si sọ pe a o ti ri iwe Idajọ papa gba, ni ọjọ 22 oṣu June mo ri waya kan lati ọdọ Eṣugbayi pe Oyinbo Major Walker ati oyinbo miran lọ fẹ wo. Major Walker ko wọ aṣọ ọba mo le pe olori Post Office ki o mu Iya waya papa wa mo ni ẹdẹ rẹ nibi.

Adajọ.—Jẹ ki nwo, Ọgbẹni Macauley fi eda na fun Adajọ, o si sọ pe ẹna ni waya na jẹ.

Ọgbẹni Macaulay,—ni ọjọ 28 oṣu June ni Eṣugbayi ranṣẹ si mi nipa ti awọn oyinbo to wa ki, Dawodu rẹ to wa l'Ọyọ pẹlu tẹ lo rin, ẹru ba mi, eyi jẹ akọkọ ti awọn oyinbo mejeji wọnyi lọ ki lati ọdun kẹta. Major Walker sọ fun Eṣugbayi pe ki o maṣe jẹ ki ẹnikẹni ji on ebe silọ titi on papa yio wa fi moto mu lọ, lẹhin kiki yi nwọn jẹ ki awọn oni nọmba ma ṣọ ile Eṣugbayi. Ọsẹ meji lẹhin eyi ni mo kọkọ gbọ nipa ti otẹ ti awọn kan ndi lati pa Eṣugbayi, emi ko ko ibi ara si agbọsọ na ni igba na. Ọdọ mokunrin kan ti a npe ni Abudu Lasisi ti o jẹ ọrẹ mi ti ki si ṣe ti Eṣugbayi Eleko wa si ọdọ mi, o wa sọ fun mi pe Eleko ki yio pada wa mọ, mo fi waya ti mo ri gba lati Ilu Ọba han, o ni Aṣoju ilu lo sọ fun on pe Eleko ko ni pada wa mọ, o ni on yio ba mi kọle, mo wi fun pe emi ko kọle ri, o ni on yio fun mi ni ṣile

mẹwa (10/-) ti Eleko ba pada wa, mo wi fun pe emi yio fun ni ad ta pọnwun (£50 ti Eleko ko ba pada wa mọ. Nitoripe o da mi loju gangan pe yio pada wa, ni ọjọ mẹta lẹhin eyi Ọgbẹni Oluṣọla ti ofin nbarojọ ati Prince Kosọkọ wa sọ fun mi ati ẹbi Dosunmu pe awọn kan nditẹ lati pa Eshugbayi Eleko ti o ba nbọ lati Ọyọ, mo sọ fun nwọn pe mo ti gbọ bẹ.

Ni ọjọ keji Lemọmu Ilu ati awọn ẹmẹwa rẹ wa si ọdọ mi lalẹ lati wa sọ ba kanna, nwọn ni ki nma dakẹ si ọro na, mo ni mo gbọ; Ni alẹ ẹwẹ mo gbọ pe nwọn ṣe ipade kan ni ile Ọbanikoro, ni ibiti ẹnikan daba pe gẹgẹ bi awọn ti gbọ pe Eṣugbayi Eleko mbọ ki nwọn mura lati da ṣanpọnna si ilu, ẹnikan si dide o ni eyi ko dara nitori aya ati ọmọ awọn le ma ba ilu yọ pẹlu ẹnikan tun dide o sọ pe nje bi o jẹ pe a ba ri ẹnikan ti yio lọ yinbọn fun u nkọ? Prince Kosọkọ sọ pe nwọn nkun moto L1173, ni P.W.D, lati mu lọ si Ọyọ, lẹhin eyi ni Lemọmu Sunmọnu sọ ti ọtẹ na fun mi mo wa dide si bi ọrọ to wuwo lẹhin igbati mo ti ri oniṣẹ Prince Eshugbayi Eleko papa mo nri Braimọh gọn firifiri o nsọ pe ki nmura si, o jẹ ọkan ninu awọn enia pataki ni Ilu Kọmiti ti nwọn nfun Eleko ni £30 o. o. loṣoṣu lati igbati Ijọba ti da owo rẹ duro. Emi lo kọ iwe ti ẹtu Ibọn na fun Ọgbẹni Oluṣọla pe ki o tẹ, o tẹ mi lọrun bẹ pe ọrọ tiyantiyan ni, o si jẹ iṣẹ awọn ọlọpa inu lati wa di rẹ.

Emi ko fi ọkan tan awọn ọlọpa inu, nitori ni ọdun diẹ sẹhin Adajọ: Nko fẹ gbọ iyẹn, Ọgbẹni Macaulay, ohun ti o wa ni ẹsẹ keji iwe na lo mu pe ki a tẹ.

Ọgbẹni Robert—Adajọ ni ẹ ba lọ si ọdọ awọn ọlọpa fun ọrọ na, o yo sọ fun Kotu idirẹ ti ẹ ko ṣe lọ.

Adajọ—Ọgbẹni Macaulay ni on ko fi ọkan tan awọn ọlọpa inu. Ọgbẹni Macaulay, nitori mo si ọdọ wọn nigbati awọn kan npete lati pa mi ṣugbọn nwọn ko ta putu.

Adajọ—A mo idi abajọ rẹ. Ọgbẹni Macaulay, mo ni igbẹ ẹle pe bi a ba tẹ si iwe irohin yio jẹ ki awọn ọlọpa inu dide si i, nwọn ranṣẹ pe Ọgbẹni Oluṣọla, o wa bi mi pe ki on lọ mo si ni ki o lọ, mo sọ fun pe ki o sọ fun wọn, ki nwọn wa ri mi nipa ọrọ yi, nwọn ko wa ri mi, awọn Ilu Kọmiti fi £200 o. o. ṣọwọ si mi ni Sunday pe awọn yio fi fun ẹnikẹni ti o ba le darukọ ẹniti o sọ pe on yio lọ yinbọn fun Eleko.

£200. o, o. na wa ni ile, mo tẹ ẹbun yi ni ọjọ Monday nkan ti ngo tun ri lẹhin eyi, ni mimu ti nwọn mu ẹniti mo gba si iṣẹ iwe irohin ni ṣiṣe, Eko labi mi emi ko kọ-kọ kọ ibi ara si agbọsọ yi ṣugbọn nigbati mo gbọ pe oyinbo meji lọ ki i mo bẹrẹ si da ẹran na ro, awọn kan ti nkọle pe Eleko yio de tabi ko ni de awon ti Eleko ni Eleko yio de awọn to wa fun Ibikunle ni ko ni de. Mo kọ iwe na lati sọ fun awọn ọlọpa inu ki nwọn ba wa idi rẹ, bi otọ ni ọrọ ọtẹ y. ki Eshugbayi ba le de si Eko ni alafia. Emi ko kọ lati fi da ilu ru, ẹjọ sun fun iṣẹju mẹdogun, ọrọ ẹkọsẹ Ọgbẹni Kester si Ọgbẹni Macaulay tẹmbẹlẹkun yi wa lati ọjọ jọjọ mo gbọ pe nwọn ran awọn ọlẹgbọn kan lọ si Ọyọ, emi ko gba ogun gbo, ọpọlọpọ ogun la ṣe si mi sibẹ emi ko ku awọn ara ilu to ngba iru nkan bẹ gbọ, ni inu oṣu May ni agbọsọ yi ti bẹrẹ mo ngbọ pe nwọn yio ṣe oju Railway ti Eleko ma wọ de ẹna waya wa fun emi ati Eṣugbayi fun ẹjọ rẹ. Eleko lo ẹna yi nigbati awọn oyinbo meji wa ki, ni ọjọ na gan ni mo pinnu titẹ agbọsọ ọtẹ na si nu iwe irohin nigbati a bẹ mi pe ki mura si otitẹ ti ọtẹ na mu mi lọkan.

Ni ọjọ 19 oṣu June lẹhin na ni ti ọtẹ Railway sisejude, ti yio wọ wa le, nko sọ pe mo gba gbọ ṣugbọn mo sọ pe o mu mi lọkan ni; ọtẹ meji lo mbẹ, moto L1173, nwọn ni nigbati nwọn ba soju rẹ de ki ẹnikan ki o yinbọn si, nigbati o ba nṣe efin, mi o gbo pe ki ẹnikan sọ pe ọkọ ilẹ ni, ti nba sọ bẹ aṣiwi ni yẹn, mi o mọ bi mọto Ọba ni ni P.W.D., emi ni kan kọ logbon ju li Eko mọ ni olusẹni ri Ọgbẹni Kester mo wa lori ibura mi a sọ fun mi pe nwọn ti kun mọto L1173 ni P.W. D., mo gba awọn ti o sọ fun gbo, emi ko gba o gbọ nisisiyi mo ka ẹmi Eṣugbayi si nkan ribiribi ati ẹjọ ti o n lọ wa ṣe pe o wuwo pupọ; atẹ iwe na si ita fun awọn ọlọpa inu. A ntẹ to ẹgba tabi ẹgbẹdogun, awọn kan wa, ti wọn nditẹ si ile Dosunmu.

Enia mọkandilogun pere ni nwọn fi ọwọ si iwe pe ki nwọn fi Ibikunle jọba, meje ti ku ninu wọn, iwe ti a tẹ tọka si awọn enia lasan kan ki ṣe awọn ti nwọn fẹ ran Eṣugbayi lo le jẹ enia lasan na, iwe na ko le jẹ ki awọn ti wọn fẹran Eṣugbayi da awọn ti ko fẹran rẹ ru. Mo mọ pe ti nwọn ba ti fi ọwọ si habiasi kopọsi Eṣugbayi yio wa le a duro de aṣẹ Ọba ti mba ọkọ ti mbọ bọ, emi ko ni fẹ sọ gbogbo nkan ti mo mọ tan nipa ọrọ yi fun ọ, ni ọkọ kọ-kọ ti o ba de ni mo nri iwe gba, Eṣugbayi ko ni wale titi nwọn yio fi fi ọwọ si iwe habiasi kopọsi, Kotu yio fi ọwọ si iwe habiasi kọpọsi, mo mọ pe Eṣugbayi mbọ ẹnikẹni mọ pe o mbọ wa si Eko ki yio lọ si orun, ni ọjọ 1 ati 15 oṣu May ni nwọn gbọ ẹjọ na ni Ilu Ọba, mo mọ pe Eṣugbayi ko ṣe Appeal pe ki on pada wa si Eko, ẹnikan npete lati pa mi mo kọ iwe si awọn ọlọpa, a tunbọ gbe ọkaunrin na ga a si san adọrin pound £70.

Adajọ.—Ọgbẹni Kester mu ẹnu kuro ninu yẹn, a o pa mi, a o ri mi pa, nitori pe mọ toju ara mi, igba pọnwun wa fun ẹnikẹni to ba mọ ẹniti o fẹ pa Eleko (£200.)

Ibere Kotu.—Ọgbẹni Macaulay awọn Ẹgbẹ Dẹmọ bẹrẹ si yọ nigbati wọn gbọ ti waya to de lati Ilu Ọba, nwọn kowo fẹto-fẹto gbogbo nwọn lo njo wọn si jẹ agbalagba ti o njo, ijo ayọ ati

obinrin, wa ni kotu ni ọjọ Satide emi ko mọ pe awọn enia bu Ọbanikoro. Iwọ Adajọ ki yio ba gbọ ẹbẹ mi bi o ba ri pe ẹnikẹni bu ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ mi a ti sọ fun olukuluku pe ki o fi ara balẹ.

Adajọ.—Ọgbẹni Macaulay o le ma lọ.

---

ORI IV.

## IṢẸ.

(*Translated from "Character by Dr Smiles"*).

APA KẸJỌ.

Southey ko kẹrẹ ninu iṣẹ ṣiṣe bakana bi Scoff. A fẹrẹ le sọ pe iṣẹ ṣiṣe wa ninu ẹsin ti o nsin Ko ju ọmọ odun mọkandinlogun lọ nigbati o kọ awọn ọrọ wọnyi.

"Ọdun mọkandinlogun! laisi ani-ani idamẹrin igba aiye mi ni; boya eyi ti o pọ ni! sibẹ, emi ko ti iṣe iṣẹ rere kan laiye. Ara oko ti o gba iṣẹ ki o ma le awọn kanakana ni kọbọ meji ojumọ ri ṣe ju, mi lọ; Ọpẹlọpẹ rẹ ni mo fi nri onjẹ ti emi ko ṣiṣẹ ti nko ṣabọ fun."

Bẹni Southey ko pa ọwọ rọ ni kekerekonranbe, ẹmo ti o kunri mọ ẹkọ iwe mimọ ni awọn Iwe ti a kọ ni ede Gẹsi nikan kọ ni o ko ni yanturu, ko kẹrẹ ninu awọn iwe ti Tasso, Ariosto, Homer ati Orid, ti a yi si ede Gesi pẹlu. Sibẹ, loju rẹ bẹnipe koi ti ṣe nkan laiye, o wa pinu lọkan rẹ pe on yio mu ọkan ṣe. O bẹrẹ, lati igbana lọ titi di igba ti o fi tẹrighaṣọ ni ko simi ni ko baye ni iṣẹ iwe ṣiṣe—gẹgẹ bi ọrọ on papa, "o nlọ siwaju lojojumọ ninu imọ lai ni imọ to bi o ti talaka to, lai talaka to bi o ti gberaga to, lai gberaga to b o ti ni igbadun to."

Awọn aṣa ti enia ba saba nda ni ifi iru iwa ti o ni han.

Ti Sir Walter Scott ni, "ki ọwọ ma dilẹ." Robertson, opitan lati igba ti o wa ni ọmọ ọdun mẹdogun ni o ti ma npa lowo pe,

Ẹniti ko ni imọ ti di oku.'

Ti Voltaire ni "Ọwọ ko dilẹ."

Eyiti Lacepede, ẹniti o nṣiṣẹ wiwadi ọ a iṣẹdalẹ enia ati ti ohun gbogbo ti a da (*Naturalist*), fẹran ju ni, "bi a ko ba ku a o ri iran wo" Aṣa kanna ni Pliny ma nda.

Nigbati Bossuet wa ni ile iwe giga (*College*) o kunri mọ iwe rẹ tobẹ ti awọn ẹgbẹ rẹ fi nda orukọ rẹ pe ni "Bos-Suetus aratro" (Malu ti ara rẹ mọ iṣẹ oko riro). "*Vita-lis*" (Aiye ni iyọnu) orukọ ti Sjoberg okọwe orin ara Sweden sọ ara rẹ gẹgẹ bi Frrderik Von Hardenberg ti sọ ara rẹ ni "Nova-lis" (Ọtun titun ni iyọnu fihan ni iru ilakaka, ati iṣẹ ti awọn ọlọgbọn mejeji yi ṣe."

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

## IROHIN ILE-IFẸ.

Ẹ jọwọ ẹ ba mi ka iwe yi bayi pe Belo ti mo sọ ni ọsẹ to koja wipe o jalaisi jẹ ọmọ Lọwa aburo Jeje ọmọ Chief Lọwa ni, ki ṣe aburo Jeje aya Prince Adeyẹmi nitori na aṣi gbe tabi aṣi kọ ki ṣe e nmọ oju -a ki Chief Lọwa, Kasunmu ati aya rẹ Princess Adelajo, Jeje ati awọn ẹbi yoku, wọn ku aṣẹyin de.

Awọn ọmọ Ọba Ọni obinrin Princesses Taiwo, Lajo ati Jolade kuro ni Ile Ifẹ ni Wednesday ijọ kẹdogbon oṣu July 1928 wọn de si Eko ni ijọ kẹrindinlogbọn oṣu yi ni Thursday pẹlu ọkọ Railway lati wa ki ẹgbọn wọn ọgbẹni E. T. Adewọyin Coker ẹniti o wa ni ile alaruu Dokita Gray ni Alli Street ni Eko—Ọgbẹni Coker pẹlu awọn aburo rẹ obinrin wọn yi lọ si okun (Beach) pẹlu Motor rẹ Morris Oxford ni ọjọ Saturday 28th July 1928. Ni ọjọ Sunday 29th July ni awọn ọmọ Ọni Ile-Ifẹ loni yi, ni wọn kuro ni Eko pẹlu Motor Lorry "Chevrolet" ti ọkọ ọmọ Ọba Taiwo ṣẹṣẹ ra pada lọ si Ile-Ifẹ, Ikọ ki kọ ẹjo lẹsẹ—Ọkọ a refo o.

Ẹnyin agbagba ile-Ifẹ. mo fẹ ki ẹ fi oju silẹ ki ẹ le ri imu, ẹyin Ifẹ na ni ẹ ma npa ni owe wipe, ajoji ki ba onilẹ du'lẹ, ṣugbọn ni ile-Ifẹ loni yi, ọmọ onilẹ ntẹ jẹjẹ ajeji ntẹ girigiri, gbogbo ọrọ mi yi ama lo bi owe bi owe, nitorina ohun ti mo npa ẹṣa rẹ ni eyi, on ni nipasẹ ọrọ ile kan ni ọja Mọdakẹkẹ eyiti o jẹ wipe ara Mọdakẹkẹ lo kọ ile na, ẹniti o ko ile tan, to wa jẹ gbese eyi ti owọ ni ọrun to wa ro wipe kosi ṣiṣe ko si ai ṣe ju wipe ile ti on kọ yi, ki on kuku gbe ta, ṣugbọn eleyi lodi si ofin Ifẹ, owa tọ ara Mọdakẹkẹ ẹgbẹ rẹ lọ ni oko,

oni ọrọ re o, mo fẹ ta ile mi, o ta fun u o gba owo, lẹhin na o tun gbe ile yi ta fun ara Ọyọ kan to wa ni Irẹmọ fun Ogoji p nun tabi ọgọjọ oke, ara ọyọ yi fun ni owo, Ọgbẹni yi wa ta ile kan fun eni meji, ara Ọyọ yi papa tun gbagbe wipe olin ko ma ta ilẹ ko si ni ile-ifẹ, o sanwo, ara ọyọ yi ni ẹniti o kọ ile si agbo ile kan ni Irẹmọ, ti awọn ọmọ onile owo, ṣugbọn loju ti wa npe bo ti wun kilẹ ṣu to alejo yio lo sile rẹ, ara ọyọ wa fi ọwọ mu ile to wa ni ọja Mọdakẹkẹ nitori wipe ọkunrin yi ṣe iwe fun wipe on ta ile na fun, bẹni awọn agbagba lo ma npa ni owe wipe "ati ẹgi ati aja onje ikoriko" ati Ile, ati Ilẹ ati ẹniti o ko gbogbo won ni ti Odua "Kabiyesi Alaşẹ Orişa" ẹniti o ko ile ara Mọdakẹkẹ ati o kọkọ ta fun ara Mọdakẹkẹ ẹniti o wa ṣe iwe fun ara Ọyọ. Ẹyin agbagba ifẹ, ọrọ re o—afi ọrọ na siwaju yin, ki ẹ yẹ wo, ki ẹ le mọ pipari rẹ, ẹniti o ba ṣe aida ki ẹ le wifun, ati wipe ohun to ba jẹ ewọ Ifẹ ki ẹ le ka fun awọn ara Mọdakẹkẹ ati pe kẹ tun sọ fun awọn ajeji miran bi ara Ọyọ yi wipe ẹniti asiki ba şi fun ni ilẹ Ifẹ oni lati tọ Ọba Oni lọ ko toro ilẹ, ki şe wipe ka ni nitori owo ka ma lọ ra ile—Njẹ awọn ara Ọyọ yi le ri ile tabi ilẹ ra ni ita Otutu? Kabiyesi, Alaşẹ Orişa,—titun nja loron, ki Ọba ko pẹ—ki Ade ma şi ni ori, ki Bata pẹ ni ẹsẹ.

Irohin kan wa wipe Ọgbẹni E. T. Adewọyin Coker nri alafia daradara ni ile alarun ti Dokita Gray ni Eko. Asi tun le s fun ọgbẹni wa yi wipe awọn ẹbi to fi si ẹhin nile Ifẹ alafia ni won wa; ati aya rẹ to şẹşẹ bimọ s wọ ati ọmọ titun ẹjẹ ọrun papa ko si nkan ni ara won. Awa nfi oju si ọna fun ọgbẹni wa yi, ko tun pada wa ba wa ni alafia.

---

Irohin iku Madam Ọlayẹmi Agege Station ati Madam Talabi Ipẹru Town.

Iba o, ẹnyin Alagba Olọlọ. Anu şe mi pupọ lati so nipa iku Madam Ọlayẹmi ọmọ ọgbẹni Ọtẹgbuyi M. Amure ologbe ti o ku ni Station Agege ni ojọ 22/7/28. Ki Olọrun Oluwa Olodumare jọwọ ba wa şe itọju awọn ọmọ rẹ Amin. Ki Ọlọrun jọwọ da aibo bo awọn aburo rẹ. Ki Olọrun jọwọ ba wa tu Iya rẹ ninu. Ki Ọlọrun jọwọ ba wa dupẹ ni ọwọ awọn Ijọ Enia dudu ti o wa ni idubulẹ ọgbẹni Okunọla nipa, ajo ti wọn şe nibi ofọ na. Adura awọn Ijẹbu nwọn ni obinrin buruku afẹ je, won ni obinrin rere afẹ ikọ. Itumọ rẹ nipe ki Olorun ma jẹki awọn ọdọmọbinrin ma fẹ ologbere-gbere ọkọ. Ki Ọlọrun jọwọ ma jẹki awọn ọdọmọkunrin ma fẹ ologbere-gbere aya buburu mọ Amin. Ki Ọlọrun ma jẹki ari iku awọn ọdọmọde mọ Amin.

Anu şe mi lati sọ nipa iku Madam Talabi ti o ku ni Ipẹru ni ojọ 26 oşu July, 1928, Talabi yi jẹ ẹni ti o ni ajo ni enia pupọ o jẹ ọkan ninu ọmọ ọba Alapẹru.

Madam Talabi ati Mr. Alli Taiwo aburo Madam Talabi nwọn jẹ olotọ enia pupọ Ki Ọlrun Oluwa Olodumare jọwọ ba wa şanu fun awọn ọmọ wọn, amin.

Ki Ọlọrun jowọ ba wa pa aşişe won rẹ tabi pa mọ amin. Ki Ọlọrun jowọ şe gbogbo ile Ọba Alapẹru ati gbogbo ohun ini rẹ ni rere titi lailai amin. Ki Ọlọrun jowọ fi anu rẹ ma ba Editor Mr. Adoye Deniga gbe.

J. A. O. SHOMADE.

---

INA WỌLE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oşupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ẹẹşẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Şango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Orişi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Şabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maşe gbẹhin ki ẹ to ranşẹ ti nyin, ki ẹ ma le j'oku ologbo.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, AUGUST 4, 1928

## ẸNIKAN KI JẸ AWADE

### ẸNYIN "AFỌBAJẸ" EKO, PẸLẸPẸLẸ O! PẸLẸPẸLẸ O!!

A gb, fenrẹn pe awọn kan npete lati tun fi ẹlomiran si ipo Prince Ibikunle Akitoye to ṣalaisi lọsẹ tokọja: bi o ba jẹ otitọ ni eyi; a nfẹ ki irufẹ awọn ẹnibẹ ṣe pẹlẹpẹlẹ, bi nkan ti ri nisisiyi ko jẹ ki awọn enia le fi ọkanjuwa la obẹ gbigbona ero wo lo wa ninu ki ẹnikan ma fi wadu-wadu ja id lori ikọ? Ohun ti o yẹ julọ nipe ki awọn irufẹ ẹnibẹ mọ pe ifẹ gbogbo Ilu lo tọ suna; jakejado gbogbo ilẹ yi kosi ẹniti ko fẹ ki Prince Eṣugbayi Eleko pada wa si ile lati wa jẹ olori wa afi awọn enia diẹ kosi si ilu kan ti o wa ti ko ni jẹ pe ifẹ inu wọn dun si ẹniti gbogbo wọn ba gba lẹsẹ mu pe on ni awọn fẹ ki o jẹ Ọba tabi olori wọn.

A ranti ọdun ti Ọba King George Ẹkarun (Kabiyesi) gbade ni ilu Oyinbo: ki a to fi ade de lori ni awọn Agbagba Oyinbo fihan ilu pe "Ọba nyin leyi ẹnyin gbogbo Gẹsi" iho ayọ nlanla ni a si gbọ pe o gba ode kan lọjọ na: eyi fihan ni pe ẹnikan tabi awọn enia bi gaga meji, mẹta ko ni ẹtọ rara lati ti ẹnikan ṣiwaju bi ogunran lọ si ọdọ awọn Alaṣẹ Ilu lati sọpe ẹniti awọn muwa niyi lati jẹ olori wọn, la laijẹ pe imọ gbogbo ilu mbẹ nibẹ.

Irufẹ iwa aitọ, iwa aiyẹ, iwa afojukamọ, ti awọn kan nsaba nma nhu lọna bayi ko le ṣe ki o ma ma da rukerudo silẹ ni ilu nkan ko ti ri bayi ni Eko ri ṣugbọn nigbati ode ti di ode awọn "Ọmọ Alukete fogun jo" ogo ni ẹdun nda ti owe ngbe

Mimu gbogbo Ilu Eko ni abori wẹrẹ ti awọn kan nmu nisisiyi nipa ṣiṣe ifẹ inu wọn nipa fifi enia joye tabi nkan miran lo nbi rudurudu ti o tan kalẹ kakiri igboro ilẹ yi loni; a ṣebi ninu awọn ti nwọn wa ninu ipo bayi ni nwọn sọ pe awọn ko fẹ ri aye tabi oku Eleko ni ilẹ yi nipe awọn yio lọwọ ninu ohunkohun ti ẹnikan ba ṣe lati maṣe jẹ ki Eleko pada si Eko mo gẹgẹb a ti ri ka ninu Iwe-irohin ojojumọ nigbati Ijọba ṣi nba Daily News rojọ ti ọran ọlẹ Ẹtu ibọn eyiti Adajọ kekere Kotu awọn Ọlọpa da ni *Monday* ọsẹ yi pe ki Oniwe-irohin na lọ san £50 tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu mẹta gẹgẹbi o ti wa ninu Iwe Idajọ na ti a ri ka ninu *Daily News* na papa; idajọ ti ko ṣai ya ẹnikẹni lẹnu nitori ẹri pọ to fun Iwe-irohin na lati jẹ ki agere ẹjọ na duro nigbati nwọn nro.

Kini ikanju ti o wa ni fifioju sun ẹlomiran ti yio rọpo Ibikunle Akitoye ti kosi? Kilo tilẹ ya apari wọn lori to mmo'kun l'odo; bi ilu ti nri ni o ri yi, inu ilu kodun si o, o nda agunla, aguntẹtẹ kaka ki o pada ninu iwa ti ko wọ fun ilu na. Igi mada o!!! A sọ fun awọn afiikanju fọba jẹ wọnyi ki nwọn lọ bara lẹ koyẹ ki gaga enia meji mẹta fẹ ohun ti kopade, ti ko wọ fun gbogbo ilu.

Ọrẹ l'a wa kun ọrẹ,
A ki wa ọta kun ọta.

---

## AYỌ ABA RA TIN-TIN.

Ọgbẹni E. T. Adewọnyun Coker, ẹniti o wa ni ile alarun Dokita Gray gba ọlọfẹ lẹ ninu mọto rẹ *morris Oxford* ni aṣale ọjọ Sunday ijọ kọkandnil-ogun oṣu July lọ si apapa, o si ni anfani lati ri iṣẹ ribiribi ti awọn oyinbo Armstrong ṣe sibẹ o si ri ọpọlọpọ ohun iyanu ni Apapa bi ile iṣẹ, awọn ẹrọ to nko ẹru tabi orişirişi nkan miran.

Ni ọjọ *Monday 30th July 1928*, ni irọlẹ o tun wọ ọkọ elefin awọn Marine to nko ero lọ si Apapa kan na, o si ba ọkọ kan na bọ on pẹlu ọmọ rẹ Abiodun eyiyi si tun fun ni oye ati aye lati ri diẹ nipa Ebute lọ si apa ọna okun ati gẹgẹ bi ọkọ elefi na ti nṣiṣẹ si. Eyiyi lo fi wa ni ọkan balẹ wipe Ọgbẹni yi nri alafia gidigidi.

Ni aṣalẹ ilọ *Thursday* ijọ keji oṣu *August*, 1928, ni Ọgbẹni wa kuro ni ile alarun Dokita Gray o si ko lọ si ile ara rẹ ni Ipayẹ Street, yio si wa ni arin wa fun ọsẹ melo kan si, ki o to lọ si ile Ifẹ.

ENIA KO DABI ALLAH.

Eko,
1st August 1928.

Si Oniwe-irohin "Eko Akete"

Iba o.

Mo juba fun gbogbo ẹnyin okoiwe inu irohin "Eko Akete" ẹ ku waju, ẹ ku iṣẹ ọwọ nyin, gege iwe na ko ni ṣe mọ nyin lọwọ, ẹni lugbadi Ijọba, aṣiri nyin, yio ma bo—emi na yio ma tọpa sẹ nyin, ire ilu yi yio gbe nyin. Ohun ti mo fẹ sọ nipa ọrọ ilẹ yi, ma fi di ọjọ miran ọjọ 're, nitorina mi o ni gba nyin ni asiko pupọ ṣugbon ma tun mọ iwe iroh n ọs sẹ ti Ijọba fun awọn ọkawe "Eko Akete" iwe irohin na ni Government Gazette, eyiti Ijọba ko akole rẹ wipe *The Nigerian Gazette Extraordinary Published by Authority No. 25 Lagos Wednesday, May 16, 1928* [ Vol 15. Eyiti aṣẹ Ọba King ni Igbimọ ti o fi fun ni ni aye nipa Igbimọ Aṣofin ti Nigeria. Ni Ile Ofin ni agbala Ọba Buckingham Palace, ni ijọ kẹfa oṣu February 1928. Eyiti Alayeluwa Ọba King papa gbe joko ni Igbimọ—Gẹgẹ bi aṣẹ ni Igbimọ ti ọjọ kọkanlelogun oṣu November, 1922, eyiti a mọ gẹge bi Igbimọ Aṣofin ti Nigeria, ni aṣẹ Igbimọ ti ọdun 1922, ti aṣẹ aye tabi ipinnu lati da Igbimọ Aṣofin fun ilu ati gbogbo agbegbe rẹ ti Nigeria gbogbogbo ti a si ni lati mọ bi Igbimọ Aṣofin ti Nigeria. Ni isinsiyi, ati wipe, Alayeluwa, nipa rẹ ati lati agbara rẹ ti o fun ni afo yi nipa iyẹn, o si tẹ ni ọrun, ati pẹlu imọran ti awọn Oṣugbo rẹ (Privy Council) lati paṣẹ ati wipe o si pa aṣẹ wọnyi :—

Ekini :—Aṣẹ yi ni a le ma pe wipe aṣẹ Igbimọ ti Nigeria ni ọdun 1928.

Ekeji :—Ikẹrin, Ikarun, Ikẹsan, Ikọkanla, Ikejila, Ikẹtalelogun ati Ikẹdọgbọn ti ofin Igbimọ Aṣofin Aṣẹ ti Igbimọ, Aṣofin ti Nigeria, 1922, a si yipada ṣugbọn laisi, Ikorira si nkan ki nkan ti a ṣe ni ẹtọ si ofin nipa awọn wonyi, ati pe aṣẹ na yio tun ṣe fun lilo fun eyiti dipo ti Ikẹrin, Ikarun, Ikẹsan, Ikọkanla, Ikejila, Ikẹtalelogun ati Ikẹdọgbọn ti ẹsẹ wọnyi, awọn wọnyi la tun tẹ sinu rẹ :—

Ikẹrin "iv. Awọn wọnyi ni yio ṣe Igbimọ na :—Governor gẹgẹ bi alaga, ko gbodo ju ọgbọn Onişẹ Ọba, enia mẹta ti ayan ti ki ṣe Onişẹ Ọba lati jẹ Aṣoju awọn enia ni Eko, ẹnikan ti ki ṣe Onişẹ Ọba lati jẹ Aṣoju ti Calabar, ati ko ma si ju enia mẹdogun ti ko ṣe Onişẹ Ọba ti Ijọba ma yan fun rarẹ pẹlu."

Ikarun "v. Awọn Onişẹ Ọba ti Igbimọ yio jẹ awọn ẹni wọnyi":—

1. Awọn ti ki ṣe ẹgbẹ Igbimọ Olotu ilu (Executive Council).

2. Onişẹ Ọba ni asiko ti o ni ẹtọ lati ma ṣe Olotu iṣẹ Marine (Dirctor of Marine) Olotu Bode Ọba (Comptroller of Customs) Aṣoju ilu (Administrator of the Colony) ati akọwe ohun awọn Yoruba (Secretary for Native affairs).

"Awọn Onişẹ Ọba ti won nşişẹ gẹgẹ bi ipo wọn bi Ajẹlẹ Agba tabi Ajẹlẹ ni gbogbo Nigeria."

Awọn Onişẹ Ọba ti nwọn nşişẹ gẹgẹ bi ipo ati ẹtọ wọn bi Igbakeji Secretary fun Ijọba, Secretary ti iwọ oron nibin, Secretary ti ila orun (Northern) Olotu iṣẹ Reluwe, Olotu iṣẹ Publice Works Department ati Olotu iṣẹ Ohun ọgbin (Agriculture.)

3. Tabi awon enia miran ti nwọn ni ipo iṣẹ ni Nigeria ti nwọn ko ju mẹta lọ lẹkan ṣoṣo (awọn ẹniti a le wipe ẹniti mẹta ti a fi sibẹ gẹgẹ bi ẹgbẹ) gẹgẹ bi Gomina ti le ṣe nigbakugba gẹge bi irinşẹ nipa ẹto gbogbo tilu, ti a le kọ tabi gba lati ọwọ Alaṣẹ Alayeluwa nipa owọ rẹ lati ọdọ Secretary rẹ papa wa (His Majesty Signified through Secretary of State) to ba jẹ wipe irufẹ ẹniti ayan bẹ fi ipo agba rẹ silẹ ni gbogbo ibişẹ ni Nigeria ijoko rẹ ni Igbimọ le şi silẹ fun elomiran.

"ix. Awọn ẹgbẹ Igbimọ le mu iwaju gẹgẹ bi Alayeluwa ba ti pa aṣẹ na tabi dipo rẹ bayi pe."

1. Ekini, awọn Onişẹ Oba ti o jẹ ẹgbẹ Igbimọ ni eto bayi :—

*a.* Awọn ẹgbe Igbimọ Aṣelu (Executive) le to ara wọn gẹgẹ bi wọn ba ti ju ara wọn lọ nipo ninu Igbimọ.

*b.* Awọn Oşişẹ ti a darukọ won ninu eto. V. (2) ninu aṣẹ yi gẹgẹ bi a ti darukọ wọn, ati pe awọn Oşişẹ ti ibişẹ Aṣelu ti Nigeria le to ipo ara wọn gẹgẹ bi won ba ti ju ara wọn lọ nipo.

*c.* Awọn ti a fi si Igbimọ (Nominated official members) gẹgẹ bi ijọ ti a gba won si tabi ti a ba gba wọn nipaşẹ eto titun wọn ni to gẹgẹ bi a ba şe to wọn.

2. Ekeji, awọn ti ilu yan ati awọn ti Ijọba fi si ti nwon ki ṣe Onişẹ Oba won ni lati to gẹgẹ bi wọn ba ti şiwaju ara wọn si ni Igbimọ tabi ti nwon ti pẹto ti wọn ti nşe bọ, ati awọn ti ilu yan ati awọn ti Ijọba gba si wọn ni lati to orukọ gẹgẹ bi ibẹrẹ ọrọ orukọ wọn ni wọn ni lati to. Tabi bi bẹ ko, ẹnikẹni ti ilu ba tun yan tabi ti Ijọba tun gba si, lẹsẹkẹsẹ ti asiko ti nwọn ni lati kọkọ şe ba pari wọn le mu iwaju ara wọn gẹgẹ bi ijọ ti ati yan won si Igbimọ ti ko şe gẹgẹ bi Igbimọ.

xi. Nigbakugba ti ẹniti ayan si Igbimọ tabi ẹniti ki şe Onişe Ọba ti o wa ni Igbimọ ti o ba ku tabi nipa aṣẹ Gomina, nipa ki kọwe lati ọwọ ara rẹ si Gomina, lati fi ijoko rẹ ni Igbimọ silẹ, tabi ki a dá duro fun igba kan lati wipe ko mọ wa pe gẹgẹ bi ẹgbẹ Igbimọ tabi ki Gomina fi han pe nipa aṣẹ ati olẹ Ijọba ti gbogbo ilu wipe ko to ẹniti o le şişẹ rẹ ni Igbimọ tabi ko tilẹ wulẹ fi ilu Nigeria

silẹ Gomina le fi otitẹ Ijọba ti gbogbo ilu yan ẹlomiran ti o ngbe arin Nigeria wipe o le jẹ Oşişẹ Ọba tabi ẹniti ki se Onişẹ Ọba ko jẹ ẹgbẹ Igbimọ, gẹgẹ bi o ti jẹ dipo tabi si aye ẹniti oku, ti o fi Igbimọ silẹ, tabi ti a da duro fun igba diẹ, tabi ti ko şe ẹgbẹ, tabi ti o fi ilu silẹ.

"Irufẹ yiyan enia bayi Alayeluwa (His Majesty) le paşẹ lati ti ọwọ (Secretary of State) Akọwe rẹ pataki wipe on ko gba yiyan na tabi ki o yipada lati ọwọ Gomina gẹgẹ bi ọna ti a wi yi.

Ẹnikẹni ti a ba yan bayi o ni lati jẹ pelu ero tabi ohun pataki ẹniti o jẹ Onişẹ Ọba tabi ti ki şe Onişe Ọba ti o jẹ ẹgbẹ Igbimọ gẹgẹ bi o ti wun ko jẹ, titi di asiko ti o jẹ yiyan rẹ ba fi di ki kọ, tabi yipada, tabi ki a yan elomiran le lori nipa aşẹ ti o mulẹ di ipo irufẹ ẹnibẹ ti o je Onişe Ọba tabi ti ki şe Onişẹ Ọba ti o jẹ ẹgbẹ Igbimọ, tabi titi di ẹniti on gba ipo rẹ eyiti a yan si ti nwọn o gba aye na de nipa idaduro rẹ tabi ki Gomina ko to fi aşẹ nipa Otitẹ rẹ ti gbogbo ilu wipe oluwarẹ ni ipa to lati şe Igbimọ ati lati şişẹ rẹ gẹgẹ bi ẹgbẹ Igbimọ tabi ki fun pada bọ wa si Nigeria.

xii. Gomina le, Ib si idaduro ko so fun Alayeluwa fun Aşẹ Itẹwọsi, tabi ki o kọ lati ọwọ Akowe rẹ pataki (Secretary of State) nipa pe gbigba ẹnikẹni ti o jẹ onişẹ Ọba tabi ti ki şe onisẹ Ọba si Igbimọ, irufẹ ẹni bẹ ni lati mu ipo rẹ ni Igbimọ nigbati Alayeluwa ba fẹ, ati pe Gomina nipa ọwọ Otitẹ Ijọba gbogbo ilu leyi irufe Gbigba na.

xxiii. O ni lati jẹ ẹtọ Gomina nipa imọran ati Aşẹ awọn Igbimọ rẹ, lati şe ofin fun alafia, Aşẹ ati Ijọba rere ti ilu ati agbegbe Nigeria eyiti a mọ ni iwo orun (Southern Provinces) irufẹ Ofin bẹ a ni lati pe "Ordinances" ati ifikun ọrọ nipa ọwọ Gomina ti Nigeria ati imọran ati aşẹ awọn Igbimọ rẹ Aşofin.

"Awọn Igbimọ na ni lati mu aşẹ won wa, ki wọn to tẹwọ bọ apo owo ati owo Nigeria fun nina, nipa sẹ awọn agbegbe gbogbo Nigeria ti a mọ bi ila orun (Northern Provinces) irufẹ aşẹ bayi ni lati to wọ ati iwe ipinnu lati han fun gbogbo Igbimọ."

xxv. Bi ofin kofin ti Igbimọ gba nipasẹ eto tabi eyikeyi ninu eto mẹta ti a kọ şiwaju ti a le so pe o yatọ si eyiti iwe Ontẹ Ijọba wa (Letter Patent) tabi aşẹ yi tabi aşẹ Alayeluwa ni Igbimo rẹ, irufẹ ofin bẹ a ni lati ka, si Iwe Otitẹ yi gba, ati pe titi a ma fi şe irufẹ ofin na ko ni lati şẹ.

"Ko si nkan kinkan ninu aşẹ yi ti o le mu tabi ko din tabi ko ni agbara lori aşẹ ti Gomina na lati şe ofin papa, nipa imọran ati aşẹ awọn Igbimọ rẹ tabi lori Gomina lori awọn agbegbe Nigeria, tabi ki o fun Igbimọ ni agbara lati şe ofin kofin ti o le kan Ilu Oke (Northern Provinces) ati gbogbo agbegbe rẹ tabi ki a şe eyiti o ma kan ilu (Colony) nipa aşẹ ninu eto xxiv ninu aşẹ Gomina tabi ki Gomina şe ofin ti o ma kan iwọ-orun (Southern Proviecces) ju eyiti a pa laşẹ ninu eto xxiv *a*."

iii. Ati pe Igbimọ Asofin ti Nigeria ti ọdun 1927, ni lati yi, yiyi na yio bẹrẹ lẹhin eto kẹrinlelogun ati pe a si mu eto xxiv *a* yi wa sinu rẹ :—

xviv. "Yio jẹ ẹtọ nipa ofin fun Gomina ti ilu ati gbogbo Nigeria pẹlu agbegbe rẹ, nipa imọran ati aşẹ awọn Igbimọ rẹ, nigbakugba nipasẹ ofin lati fun ni ni alafia, Aşẹ ati Ijọba rẹ fun gbogbo ilu Nigeria ati fun gbogbo enia inu rẹ ni ọna bayi :—

*(a)* "Wipe irufẹ ofin kofin ni lati je imọran ati aşẹ awọn Igbimọ, ni eyiti o jẹ mo iwọ-orun ati agbegbe rẹ (Southern Provinces of the Protectorate) ati pe ofin a ni lati la si iwaju ati ọwọ Gomina ti ilu ati gbogbo Nigeria nipa imọran ati aşẹ Igbimọ gẹgẹbi ilana ti o wa nipa agbegbe ilu—

*(b)* Nipasẹ ọran wọnyi ti ni aye ati pe aye ti a fun Nigeria ati agbegbe rẹ nipa aşẹ Igbimọ ti ọdun 1922, ti o kan nipa şişe ati dida ofin silẹ lati ọwọ Gomina ti gbogbo agbaye Nigeria ni Odo-Ọya (Northern Provinces) ni lati tọka si gbogbo ofin ti Aşẹ nipasẹ aşẹ ninu eto yi ni gba to je ti a le wipe wọn şe nipa aşẹ ti Nigeria ati agbaye şe ni Igbimọ ni ọdun 1922.

*(a o ma ba bọ)*

Emi ni ti nyin nitotọ.

ENIA KO DA BI ALLAH

## *Olusakin's Column.*

**The Appointment of Dr. Cosmo Lang as Archbishop of Canterbury.**

The Most Reverend Cosmo Gordon Lang, D.D., D.Litt., D.C.L., L.L.D., Archbishop of York, has been appointed Archbishop of Canterbury.

**St. Paul's Church Breadfruit.**

It was just a year ago, that is, on Friday the 29th July, 1927, when the renovation of St. Paul's Church Breadfruit was dedicated by the Bishop of Lagos, F. Melville Jones, D.D. A Thanksgiving Service was held on the occasion by the Parishoners at 5 p.m., on Sunday last the 29th July, 1928, when Rev. C. A. Sowunmi, M.A., the

Curate occupied the pulpit and preached an impressive sermon. An Anthem was nicely rendered by a mixed Choristers (male and female voices).

We congratulate the Venerable Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, Lth. the Pastor, for his organizing genius and ability. The collection was in the neighbourhood of £9.

### Arrival.

The Right Rev. Bishop A. W. Howells, M.A., D.D., of the Niger, arrived Lagos, from England by the Steamer *R M.M.L Adda*, on Thursday, the 2nd August, 1928. Ẹ ka bọ, alafia kẹ de bi.

### Judgment on the Great Gun Powder Plot Case.

On Monday morning, the 30th July last, at the Police Magistrate Court, Lagos, at 9 30. a.m., the public was marvelled at the judgment delivered by His Worship Henry Alfred Young, K.C., Police Magistrate, in the Great Gun Powder Plot Case, imposing a fine of £50, or indefault 3 months' simple imprisonment on the Editor of the *Lagos Daily News*, Mr. J. A Olușọla.

### The Death of Prince Ibikunle Akitoye.

The death took place of Prince Ibikunle Akitoye, at his residence, King Street, after midnight of the 26th July, 1928.

His mortal remains were removed and laid in (state) at Iga Idunganran where he was buried on Friday, the 27th, at 4.30 p.m.

A good number of sympathisers including the family of the deceased were present at the funeral amongst whom were Chiefs Obanikoro, Ọjọra, Oniru and Onitana; Sanni Adewale, Belo Pẹpẹ, Yesufu Owo, Karimu Kọtun, Mr. J. Akiyẹmi Oshodi who carried the Staff, and others.

The officiating Clergies were Rev. Superintendent D. A. Hughes, Revs. J. F Ogunko and E, Ayọ Salu of the United African Church, Lagos and Ebute Metta. To the breaved family in general, our condolence.

### Thy Will Be Done.

It is with deep regret we have to announce the death of Mrs Patience Orẹ Savage, wife of Mr. Benjamin Akin Savage at her grandfather's house at the corner of Broad and Balogun Streets, on Friday early in the morning, the 27th July, 1928, at 5.45 a.m, two hours after childbirth. The deceased was a sister of the Honourable S. H. Pearse, F.R.G.S.

We understand that the Baby Girl is alive and doing well.

To the breaved husband and relatives of the deceased, we tender our heartfelt sympathy.

### Birth.

We congratulate Mr & Mrs. Christian Kumolu Johnson, Law Student, Inner Temple, London, (and Late Editor of the *Nigerian Chronicle*) Lagos, for the safe delivery of a female child in London, on Thursday, the 21st June, 1928. We learn by the last mail that both mother and child are keeping good health.

### Christening.

The Christening ceremony of Christiana Olurẹmi Ibironkẹ and Michael Ọlatunji Shomeye: and Alfred Afolabi Shobọh, took place on Wednesday, the 1st August, 1928, by the Rev. Evan E. Williams, M.A., at wesleyan Olowogbowo Church, at 6.30 p.m.

Mr. & Mrs. Michael S. T. Shobọh of No. 1, Alade Lane, Lagos, were "At Home" on the same evening to few friends and relatives, when several palatable dishes were laid on the table and drinkables served.

We say to Mr. & Mrs. Shobọh "Ẹ ku inawo, ki Oluwa ki o da gbogbo awọn ọmọ ati ẹgbọn wọn si.

### Nigerian Railway African Staff Outing. 1928.

In connection with the above, we learn that there will be a Tennis Tournament on the Railway African Staff Tennis Grounds, Ondo Street, Ebute Metta, on Saturday, the 4th August, 1928, at 4 30 p.m., and Sports on Monday, the 6th instant, on the Railway Golf Course (at the back of the General Offices) Ebute Mẹtta, at 3 p.m., to be followed by Dance at the Glover Memorial Hall, on Friday, the 10th August, at 9 p.m.

Hostess Mrs. S. M. Bucknor. We wish them every success.

OLUȘAKIN.

## KERE O!

Mr. C. B. SHODIYA, *Produce Buyer*, ti No. 132, nitosi Niger Company, Ebute Ero, ni ọpọlọpọ Tapo (Tapaulin) siye 15 x 15 fun hihaya, bi o fẹ ṣe ariya ti Iyawo lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe Wolmọ lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe ariya nipa ti oku lọ sibẹ, o wa fun ẹnikẹni ọpọku-ọyọku ni owo hihaya rẹ.

9d. ẹgbẹdogun fun Tapo kan lojumọ.

C. B SHODIYA,
*Produce Buyer*.
132, Ebute Ero,
Marina, Lagos.

## Advertisement.

Vacancies occur at Ijora and other Stations in Nigeria for a number of experienced boiler house engine from attendants.

Applications will only be considered from men having previous experience with high pressure boilers and high speed reciprocating steam engines.

Commencing Salary from £72 to £88 per annum, according to qualifications.

Full particulars of experience and training should accompany applications, which should be in writing and addressed to the Director of Public Works, Lagos.

## Attention ! Attention ! ! Attention ! ! !

FOR BUYERS IN GENERAL.

HAVE YOU BEEN AT

IWA-JO-WA STORE, (No. 1 & No. 2)

IF NOT, WHY NOT? AN OPPORTUNITY ONCE LOST CAN NEVER BE REGAINED.

The undersigned have in Stock for sale at unbeatable—prices not obtainable else-where

The following cheapest materials are kept in Stock.

**Rubby, Rubby, Rubby !**

*( Again and again, "Gbangba dẹkun" Kedere bẹ wo. )*

**Goldsmith Tools :—**

Pickers, of any kind or size
Plowpipes, of any kind or size
Scisscrses, do.
Drawplates, do.
Brass mouldings, do.
Hand Scale, do.
Brass Lamps, do
Screw Plates, do.
Cutting and doming punches of any kind or size.
Assorted kinds of Files,
Bellows of any description

Bench Vices, of any description
Crusibles, do.
Kegs of saltpetre,
" " Alum,
" " Borax
Pure Silver grains, too numerous to mention.
Capentory Tools of any description
Shoemakers, do.
Sawyers, do.
Bricklayers tools of any description
Bicycle accessories do. etc. etc.
Seeing is believing;

"*Ganni ya fi ji.*" Irọhin ko to afojuba.

Apply to Proprietors D. ODUSANYA & BROS.,
*Expert Goldsmiths.*

45, Princes Street. Isalẹgangan, Lagos,
20, Victoria Street, Lagos.

*Cable Address :—*
**Iwajowa Store No. 1.**
45, Princes Street, Lagos.

We are sole local Agents for

VIBRONA

The Ideal Tonic Wine.

SURPASSES ALL OTHER WINES

AS A

TONIC STIMULANT

AND

INVIGORANT.

**VIBRONA** has been justly described as the **Supreme Tonic**, and the world-wide reputation which it enjoys is mainly due to the personal testimony of those who, having experienced its remarkable energising powers, are glad to recommend it to their friends.

A liqueur-glass of VIBRONA, taken either alone or with a plain biscuit, is almost magical in its effect as a Tonic Restorative.

The modern Discovery for Female sufferers is

**Wireless Female Pills**

A sure remedy against all kinds of monthly disorders experienced by women, and an effective vitaliser against harreness.

4/6 per bottle of 72 Pills.

**Kaduna Balm 1/-**

The family Remedy applicable in 100 different ways. Indispensable during this rainy season.

**Saccharine 1/-, 1/6**

**Anti-Rheumatic Salt 2/- and 3/6**

**Rheumatism Pills 1/6**

**Yaro** (*small and large*) **2/3 & 3/3**

**Pile Pills 1/6**

**Pile Remedy 7/6**

**Cooling Blood Purifier 7/6d.**

(A powerful blood cleansing Preparation).

**Gonorrhea Remedy 7/6 & 4/6.**

Works with effective rapidity.

***Dr. De Roos' concentrated Guittae Vitae for general Debility, shaking of the hands and limbs, dimness of sight &c., miraculous curer, largest size £2. 2. 0.***

Special Wholesale Price.

*Obtainable at:—*

**IYIN OLUWA MEDICINE STORES**

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,

*Branches*:—6, Martins Street,

41, Alli Street, Faji Market,

109 Griffith Street, Ebute-Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

## AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Şugbon nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ję ki ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işę ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splendid Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B.:—Not obtainable elsewhere.*

## GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fę baję, ati orişirişi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

## WHITE'S WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the [illegible] in such a way, that the regular user is able to [illegible] many times the usual amount of Brainwork [illegible] he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is [illegible] boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE [illegible]
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

## EGBOGI ISOYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişę ati gbogbo awọn ti o ba [illegible] lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy of Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist*,
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

## EGBOGI ILANA ĘJĘ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rę mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşę Ewurę pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ęyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ęsanri ni akoko bela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Ioloke Mone, A & D. Bula Matadi for health-restoring purposes : these Medicines are on sale at Mr H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same,* if any

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE,
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Ofin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undertaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to — A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

**ILE OWO OYINBO**

# JOHN RADCLIFFE

**Ni No. 63, Ebingbeti, Eko.**

———:o:———

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmi ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọ si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi ati awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.